# AWỌN AJAKALẸ-ARUN NAA TUBỌ N BURU SI I

## Ẹksodu 8:20-32; 9:1-12

## ẸKỌ 54 – FUN AWỌN ỌDỌ

**AKỌSORI: "Idajọ enia li o nti ọdọ OLUWA wá" (Owe 29:26)**

**Agbara Awọn Alalupayida di Asán**

Ni akoko ti ajakalẹ-arun kẹta wá sori Egipti, awọn alalupayida ri i pe wọn kò lagbara lati ṣe afarawe iṣẹ ti Mose ṣe. A sọ agbara diẹ ti wọn ni paapaa di asán, a kò si tun gbọ́ pe wọn ṣe iṣẹ-iyanu miiran mọ́.

Ṣugbọn Ọlọrun ṣẹṣẹ bẹrẹ lati maa fi agbara iṣẹ-iyanu Rẹ̀ hàn ni. A ranti bi O ti wi tẹlẹ pé Oun yoo fi Ẹni ti Ọlọrun i ṣe han awọn ara Egipti bi wọn si ti n sé ọkàn wọn le si i bẹẹ ni Oun tubọ n rán awọn ajakalẹ-arun ti o buru si wọn.

**Ọpa Ọlọrun ki I ṣe Ọpa alupayida**

Ninu iṣẹ-iyanu kin-in-ni, Ọlọrun sọ fun Mose pe ki o sọ ọpa rẹ̀ silẹ, o si di ejò. Ninu ajakalẹ-arun kin-in-ni ati ekeji, o na ọpa rẹ̀ sori omi; ninu ajakalẹ-arun ẹkẹta Mose fi ọpa rẹ̀ na ilẹ̀, erupẹ si di ina-ori. Ṣugbọn ninu ajakalẹ-arun mẹta ti o tẹle e, a kò gbọ́ nnkan kan nipa ọpa naa mọ́. Ki i ṣe ọpa alupayida yii ni o le ṣe iṣẹ-iyanu kankan; ṣugbọn agbara Ọlọrun ti o ti ọpa naa lẹyin ni o ṣe iṣẹ-iyanu naa. Nigba ti Ọlọrun fẹ fi eṣinṣin ba ilẹ naa jà, O wi pe wọn yoo fara hàn ni ọjọ keji, o si ri bẹẹ lai si aṣẹ kankan lati ọdọ Mose. Agbara Ọlọrun kò mọ si lilo ọpa nikan.

**Iyasọtọ awọn Eniyan Ọlọrun**

A tun ri ifarahan miiran nipa agbara Ọlọrun ninu ajakalẹ-arun ti o tẹle lakoko yii. O dabi ẹni pe awọn ajakalẹ-arun mẹtẹẹta akọkọ wá sori awọn Heberu pẹlu, ṣugbọn bi wahala wọnyii ti n pọ̀ si i, Ọlọrun ya awọn eniyan Rẹ̀ kuro lara awọn ara Egipti, O si yọ wọ́n kuro ninu ìṣẹ́ oró ti awọn ọta Ọlọrun ni lati là kọja.

Bi o ba ṣe pe eyi jẹ iru ajakalẹ-arun ti n bọ̀ wa ṣẹlẹ tẹle e, ti i ṣe arun ti o pa ọ̀wọ́ maluu, a le wi pe kò tàn de ilẹ Goṣeni. Ṣugbọn taa ni le dá awọn eṣinṣin duro lati má lọ si ibi ti wọn ba fẹ lọ? Ọ̀wọ́ eṣinṣin pupọ ni o wà; wọn wà ninu gbogbo ile ati lori gbogbo ilẹ naa. Ko si aalà kan laaarin Goṣeni ati iyoku ilẹ Egipti ti awọn eṣinṣin wọnyii le ri. Ki ni ṣe ti omi okun nla ti o gun to ẹgbẹẹgbẹrun mile kò bo ori ilẹ, paapaa julọ nibi ti bebe okun tẹju ti kò si si ohun ti yoo dá omi naa duro? Nitori Ọlọrun ti wi pe, "Nihinyi ni iwọ o dé, ki o má si rekọja, nihinyi si ni igberaga riru omi rẹ yio gbe duro mọ" (Jobu 38:11). Pẹlupẹlu, awọn ara Egipti ni lati kọ́ nipa Ẹni ti Ọlọrun Alagbara I ṣe ! Nitori naa Ọlọrun fi awọn eṣinṣin wọnyii si ibi ti O n fẹ ki wọn wà.

**Farao Jọ̀wọ́ Silẹ̀ Laabọ̀**

Awọn eṣinṣin mu ipọnju pupọ bá Farao, o si ranṣẹ pe Mose ati Aaroni lati wa gbà ilẹ naa silẹ lọwọ ajakalẹ-arun yii. O ṣeleri fun wọn pe wọn le ṣe irubọ wọn, ṣugbọn oun fẹ ki wọn duro ni Egipti lati ṣe e. Awọn Ọmọ Israẹli kò le ṣe eyi fun idi pupọ. Lọna kin-in-ni, Ọlọrun ti sọ fun wọn lati lọ si aginju, wọn si gbọdọ gbọran si I lẹnu patapata. Nigbooṣe nigba ti a fi Ofin fun Israẹli Ọlọrun tẹnu mọ ọn pe Oun kò fẹ ki awọn ọmọ Oun sin ni ibi kan ṣá, ṣugbọn ni ibi ti Oun ti yàn nikan (Deuteronomi 12:11; 14:23; 15:20; 16:2).

Idi miiran ni pe awọn ara Egipti n sin awọn ẹran ti awọn eniyan Ọlọrun fi n rubọ; bi awọn Ju ba si pa awọn ẹran wọnni loju awọn eniyan ilẹ naa, wọn yoo ri ibinu awọn ara Egipti. O dabi ẹni pe Farao ri si eyi, nikẹyin o si gbà pe ki wọn lọ si aginju bi wọn kò ba ni rìn jinna. Ṣugbọn lẹsẹkẹsẹ ti eṣinṣin naa lọ -- ko tilẹ si ẹyọ eṣinṣin kan ti o kù silẹ nigba ti Ọlọrun mu wọn kuro – Farao kò mu ileri rẹ̀ ṣẹ mọ́. A kò le gbẹkẹle ileri awọn eniyan buburu rara.

**A Tabuku si Maluu Iyasọtọ**

Awọn ti n ṣe awari awọn nnkan ti o ti ṣẹlẹ sẹyin nipa wiwa ilẹ ti ri ọpọ akọle ni Egipti o fi hàn pe awọn ara Egipti maa n sin oriṣiriṣi oriṣa, o kere tan ẹgbọ̀kọnla (2,200). Ọ̀kan ninu awọn oriṣa pataki ti wọn n sin ni wọn wi pe, o maa n wá si ayé nigba miiran ninu awọ maluu; nitori bẹẹ awọn eniyan ko le pa maluu rara nitori ibẹru pe ki wọn ma ba a pa ọkan ninu awọn oriṣa wọn. Ni India lonii, a fun "maluu mimọ" laye lati rin kiri oju ọna òpópó, ati sinu ile itaja paapaa lai jẹ ẹ niya. Nigba ti ajakalẹ-arun ẹkarun wá sori Egipti, gbogbo awọn ẹran ti o wulo ni o kú, ati maluu awọn ara Egipti pẹlu. Ọlọrun wa kò ka awọn oriṣa wọn si, O si sọ agbara ti wọn rò pe wọn ni di òfo.

Farao mọ̀ pe awọn ọmọ Heberu yoo lo maluu ati agutan fun irubọ si Ọlọrun wọn, nitori naa o rán ẹni kan lati lọ wò bi maluu kan ba wa laaye ni Goṣeni. Kò si ọkan ti o kú ninu awọn ẹran wọn! Ṣugbọn sibẹ Farao sé ọkàn rẹ̀ le si Ọlọrun, oun ko si jọwọ́ silẹ.

A mọ pe awọn eniyan wa lonii ti wọn pinnu ninu ọkàn wọn lati ṣe ibi, bi Ọlọrun si ti n mu wọn la wahala kọja to, bẹẹ ni inu n bi wọn si i. Dipo ki wọn kigbe pe Ọlọrun fun aanu, wọn n fi Ọlọrun ré nitori ipọnju wọn. Wo bi idajọ ti o n duro de iru ẹni bẹẹ ti lẹru tó!

**Oowo Kikan lara awọn ara Egipti**

Ajakalẹ-arun ẹkẹfa ti o wá sori awọn ara Egipti ni oowo, ki i ṣe lara awọn eniyan nikan, ṣugbọn lara awọn ẹranko pẹlu. Bi iwọ ba ti ni oowo rí, iwọ yoo mọ iru irora nla ti ajakalẹ-arun oowo yii mu ba wọn. Iwe Mimọ́ ko sọ fun wa boya Mose sọ nnkan kan fun Farao nipa ipọnju ti o n bọ wa yii; ṣugbọn o duro niwaju ọba o si ku eeru si oju ọrun ti o di ekuru lẹbulẹbu ti o fẹ si gbogbo ori ilẹ Egipti – afi Goṣeni nikan ni kò fẹ́ si – o si jẹ ki arun oowo naa bẹ́ jade. Dajudaju Mose ati Aarọni rin kiri laaarin ekuru yii pẹlu, ṣugbọn oowo kò sọ wọn rara nitori Ọlọrun tọju wọn.

Awọn alalupayida paapaa kò lagbara lati mu ki oowo naa má sọ awọn tikara wọn, oowo naa si mu wọn kikankikan to bẹẹ ti wọn kò fi le duro niwaju Mose. Wọn ti sin Satani tọkantọkan, ṣugbọn ki ni ere ti wọn ri gbà? Ki-i ṣe pe Satani yoo jẹ ki awọn eniyan gba eke gbọ nikan, ṣugbọn lẹyin ti wọn ba ti sin in tọkantọkan, oun yoo fi irora ati wahala pupọ san an pada fun wọn; nikẹyin wọn yoo si gba idajọ Ọlọrun ti o wuwo jù lọ.

Ninu gbogbo iyiriwo wọnyii a le ri aanu Ọlọrun fun awọn ẹlẹṣẹ. -Oun I ba ti da ọpọlọ wọn rú, tabi ki O pa wọ́n lẹṣẹkẹṣẹ patapata, ṣugbọn O fun wọn ni àye sibẹ lati ronupiwada. -O n fi agbara Ọlọrun otitọ hàn wọn, ki wọn má ba ṣe awawi pe aimọ ọna ti o tọ́ ni o jẹ ki awọn ṣegbe.

**AWỌN IBEERE**

1. Darukọ ajakalẹ-arun ẹkẹrin, ẹkarun-un ati ẹkẹfa.
2. Njẹ dandan ni ki Ọlọrun lo ọpa ki O to le mu awọn ajakalẹ-arun wá?
3. Ki ni ṣe ti awọn eṣinṣin naa kò dé ilẹ Goṣeni?
4. Njẹ a le gbẹkẹle ileri awọn eniyan buburu?
5. Ki ni ṣe ti o jẹ iyanu fun awọn ara Egipti nigba ti awọn maluu wọn kú?
6. Ki ni mu oowo wá sara awọn eniyan naa?
7. Njẹ awọn alalupayida le mu ki oowo naa má wa sara awọn tikara wọn?